# Fidiò lẹ́yìn àkọlù inú ìjọ ní Nigeria

2022-011-IG-UA

## Ọ̀rán naa ní Ṣókí

Ìgbìmọ̀ naa ti ṣe ayipada sí ipinnu Meta lati yọ fidiò kan lori Instagram ti o nṣe afihan abajade akọlu aṣẹ̀rùbàlú kan ni Nigeria kuro. Ìgbìmọ̀ naa rii pe dida atẹjade naa pada pẹlu oju iworan ikilọ kan ndaabo bo aṣiri awọn ti o fi ara káàṣá nigba ti a nfi aaye gba ijiroro awọn iṣẹlẹ ti awọn ipinlẹ kan le maa wa ọna lati pani lẹnu mọ.

**Nípa ọ̀ràn náà**

Ni Ọjọ 5, Oṣu Kẹfa, Ọdun 2022, olulo Instagram kan ni Nigeria gbe fidiò kan jade ti o nṣe afihan awọn eniyan ti ko le mira, wọn sun nilẹ ninu àgbàrá ẹ̀jẹ̀. Ó jọ abajade akọlu ìṣẹ̀rùbàlú kan ninu ijọ kan ni guusu iwọ oorun Nigeria, ninu eyi ti o kere tan 40 [ogoji] eniyan kú ti ọpọ awọn ti o ju bẹẹ lọ fi ara pa. Wọn gbe àkóónú naa jade ni ọjọ kan naa ti akọlu naa waye. Lara awọn àsọlẹ́ ti wọn gbe jade naa ni a ti ri adura ati awọn gbolohun nipa aabo ni Nigeria.

Awọn ẹrọ Meta ti o nfunra wọn ṣiṣẹ ṣe agbeyẹwo àkóónú naa wọn si ṣe amulo oju iworan ikilọ kan. Sibẹsibẹ, a kò ta olulo naa lólobó niwọn bi awọn olulo Instagram kii tii gba afiyesi nigba ti a ba ṣe amulo awọn oju iworan ikilọ.

Lẹyin naa ni olulo naa wa fi akọle kan sori fidiò naa. Eyi ṣe apejuwe iṣẹlẹ naa gẹgẹ bi “sad” (eyi ti o bani ninu jẹ),” ó si lo ọpọlọpọ haṣitaagì, lara eyi ti a ti ri awọn itọkasi awọn ti o nko ohun ija jọ, ohun to jọ dídún ibọn, pẹlu ere idaraya kan “airsoft” (nibi ti awọn ẹgbẹ elere idaraya ti ndije pẹlu awọn àgbélẹ̀rọ ohun ija). Olulo naa ti fi iru awọn haṣtaagì kan naa si ara ọpọlọpọ awọn atẹjade miran.

Ni kete lẹyin rẹ, ọkan lara awọn ibi ifipamọ Iṣẹ Ifiwera Iroyin Meta, tii ṣe irufẹ “escalations bank (ibi ifipamọ ìfẹ̀lójú) kan,” da fidiò naa mọ, ti o si yọ ọ kuro. Awọn ibi ifipamọ Iṣẹ Ifiwera Iroyin le funra wọn fi awọn atẹjade olulo we àkóónú yoowu ti a ti ri pe o ntapa si ofin tẹlẹ. Awọn ikọ akọṣẹmọṣẹ abẹle Meta ti rii pe akoonu inu “escalation bank” (ibi ifipamọ ìfẹ̀lójú) kan ntapa si ofin. Àkóónú yoowu ti o ba dabi awọn yii ni a o dá mọ̀ ti a o si yọ kuro lọgan.

Olulo naa bẹ Meta nipa ipinnu naa, ti eniyan kan ti o jẹ oluyẹwo si fi ọwọ si yiyọ kuro naa. Lẹyin eyi ni olulo naa tun bẹ Ìgbìmọ̀ naa.

Nigba ti Ìgbìmọ̀ gba ọran naa, Meta ṣe agbeyẹwo akoonu naa ninu “escalations bank (ibi ifipamọ ìfẹ̀lójú),” wọn si rii pe o ntapa si ofin, wọn si yọ ọ kuro. Sibẹsibẹ, wọn gbe ipinnu wọn lati yọ atẹjade naa kuro lẹyin ninu ọran yii, wipe a le ka awọn haṣtaagì

naa si eyi ti o “glorifying violence and minimizing the suffering of the victims (ngbe oriyin fun iwa ipa ti o si nfi oju tẹmbẹlu inira awọn ti o fi ara kááṣa naa).” Meta rii pe eyi tapa si ọpọlọpọ awọn ilana, titi kan ilana Àkóónú Iwa Ipa ati Aworan, ti o fi ofin de awọn ọrọ ti o nbani lọkan jẹ́.

**Àwọn kókó àrígbámú**
Eyi ti o pọju ninu awọn ọmọ Ìgbìmọ̀ rii pe dida akoonu yii pada si Instagram wa ni ibamu pẹlu awọn Òdíwọ̀n Awujọ Meta, amuyẹ pẹlu awọn ojuṣe ẹtọ ọmọniyan.

Nigeria nla oniruuru awọn akọlu ìṣẹ̀rùbàlú kọja lemọlemọ ti ijọba Nigeria si ti pa igbejade awọn kan lara wọn lẹnu mọ, bi o tilẹ jẹ pe ko dabi ẹni pe wọn ṣe bẹẹ ni ti akọlu Ọjọ 5, Oṣu Kẹfa Ọdun. Ìgbìmọ̀ naa fi ara mọ ọ pe ni iru awọn aaye yẹn ominira sisọ ero ọkan ẹni diidi ṣe pataki.

Nigba ti wọn ko ba da awọn haṣtaagì naa ro, Igbimọ naa fi ẹnu ko pe ki a ṣe amulo oju iworan ikilọ sori fidiò naa. Eyi yoo daabo bo aṣiri awọn ti o fi ara kááṣá, eyi ti oju awọn kan ninu wọn hàn, nigba ti a ba nbọwọ fun ominira lati sọ ero ọkan ẹni. Ìgbìmọ̀ naa ya fidiò yii sọtọ kuro lara aworan inu ọran “Russian poem (ewi ilẹ Russia),” tí aworan rẹ ko to eyi, nibi ti Ìgbìmọ̀ ti rii pe ko nilo oju iworan ikilọ. Wọn tun ya a sọtọ kuro lara aworan inu ọran “fidiò aworan ilẹ Sudan,” ti o tubọ ni aworan ni ọna ti o jọju, nigba ti Ìgbìmọ̀ naa fi ara mọ ipinnu Meta lati da àkóónú naa pada pẹlu oju iworan ikilọ, ṣiṣe amulo “aaye yiyẹ fun iroyin,” ti o nfi aaye gba àkóónú ti o ntapa si ofin ni ọna miran.

Eyi ti o pọju ninu awọn ọmọ Igbimọ naa rii pe ó ṣì fi si apa ọdọ dida akoonu naa pada nigba ti wọn ba gbe awọn haṣtaagì naa yẹwo, bi o ti jẹ pe nṣe ni wọn nsọ awọn eniyan ji ti wọn ko si bani lọkan jẹ́. A saba maa nlo awọn haṣtaagì lati gbe atẹjade kan larugẹ ninu awujọ kan. Awọn ajuwe inu ẹrọ Meta maa nṣe iwuri fun eyi, nitori naa o yẹ ki ile iṣẹ naa ṣọra nipa fifi oju laifi wo lilo wọn. Awọn ti o pọju ninu wọn kiyesii pe Meta ko ka awọn haṣtaagì yii si eyi ti wọn lo lati fi àrékérekè fini ṣe ẹlẹya. O dabi ẹni pe o ye awọn olulo ti o nsọ àsọlé nipa atẹjade naa pe lati sọ awọn eniyan ji ni o wa fun, ti awọn ifesi si ẹni ti o tẹ ẹ jade si ba awọn ti o fi ara kááṣá kẹ́dùn.

Awọn perete ninu Ìgbìmọ̀ naa rii pe fifi awọn haṣtaagì ti o nii ṣe pẹlu ibọn yiyin kun fidiò naa fẹ jọ eyi ti o le bani lọkan jẹ, o si le fa ipaya fun awọn ti o mori bọ́ pẹlu awọn idile awọn ti wọn fi ara kááṣa iṣẹlẹ naá. Oju iworan ikilọ ko nii le din imọlara yii ku. Ti a ba wo bi iwa ipa iṣẹrubalu ti ri ni Nigeria, Meta jare ni kikiyesara, paapaa nigba ti a le da awọn ti wọn fi ara kááṣá mọ. Nitori naa awọn perete rii pe ko yẹ ki a da atẹjade yii pada.

Ìgbìmọ̀ naa rii pe o yẹ ki a tan imọlẹ si ilana Àkóónú Iwa Ipa Ati Aworan. Ilana naa fi ofin de awọn ọrọ ti o nbani lọkan jẹ,” sibẹ itumọ akanlo ọrọ yẹn ti o wa lara itọni abẹle fun awọn oluṣeto fẹ̀ ju bi a ti nlo o ni gbogbo igba lọ.

Ìgbìmọ̀ naa kiyesii pe a yọ àkóónú naa kuro tẹlẹ nitori pe o ba fidiò kan mu ti wọn ṣeeṣi fi kun ibi ipamọ ìfẹ̀lójú. Ni abajade laasigbo naa, o ṣeeṣe ki Meta maa gbiyanju lati rii daju pe àkóónú ti o ntapa si ofin ko maa tan kaakiri awọn oju atẹ rẹ̀. Ṣugbọn, ile iṣẹ naa gbọdọ wa rii daju bayii pe a da àkóónú ti a ṣeeṣi yọ kuro pada, ki a si da awọn ijiya ti o tẹle e pada.

**Ìpinnu Ìgbìmọ̀ Májẹ̀-ó-bàjẹ́**

Ìgbìmọ̀ Májẹ̀-ó-bàjẹ́ yi ipinnu Meta lati yọ atẹjade yii kuro pada wọn si rii pe o yẹ ki a da a pada si oju atẹ naa pẹlu oju iworan ikilọ “disturbing content (àkóónú ti o nda ọkan ru)”.

Ìgbìmọ̀ naa da aba pe ki Meta:

- Ṣe agbeyẹwo ede ti wọn lo ninu ilana Àkóónú Iwa Ipa ati Aworan lati rii daju pe o wa ni ibamu pẹlu itọni abẹle fun awọn oluṣeto.

- Fi to awọn olulo Instagram leti nigba ti wọn ba da oju iworan ikilọ bo àkóónú wọn ki wọn si pese eredi ilana ni pato fun ṣiṣe bẹẹ.
- 

*Awọn ikadii ọran maa npese agbeyẹwo nipa ọran naa wọn ko si ni iwulo fun itọkasi.

## Ìpinnu ọ̀ràn lẹ́kùnrẹ́rẹ́

**1. Ìkádìí ìpinnu**

Meta yọ atẹjade Instagram kan ti o ni fidiò alakọle kan ti nṣe afihan abajade akọlu kan ninu ijọ kan ni Nigeria kuro, fun titapa si awọn ilana rẹ lori Àkóónú Iwa Ipa ati Aworan, Ihalẹ ati Ìdúnkokò Mọ́ni, pẹlu awọn Ẹnikọọkan ati Ajọ Elewu. Eyi ti o pọju ninu awọn ọmọ Igbimọ rii pe o yẹ ki wọn da akoonu naa pada si oju atẹ naa pẹlu oju iworan “disturbing content (akoonu ti o nda ọkan ru)”, eyi ti o nfẹ ki awọn olulo tẹ sori rẹ lati ri fidiò naa. Awọn perete ninu Ìgbìmọ̀ naa ko fi ara mọ ọ wọn yoo si mu ipinnu Meta lati yọ àkóónú naa kuro ṣẹ.

**2. Àpèjúwe àti ìpìlẹ̀ ọ̀ràn**

Ni Ọjọ 5, Oṣu Kẹfa, Ọdun 2022, awọn aṣẹ̀rùbàlú ṣe akọlu si ijọ Katolikì kan ni Ọ̀wọ̀, guusu iwọ oorun Nigeria, ti wọn pa ó kere tan 40 [ogoji] eniyan ti nnkan bi 90 [aadọrun] eniyan si fi ara pa. Laarin wakati diẹ ti akọlu naa ṣẹlẹ, olulo Instagram kan ni Nigeria gbé fidio kan jade lori akanti gbangba rẹ eyi ti o jọ abajade naa, ti o nṣe afihan awọn oku ti ko le mira ti o ṣe kiki ẹ̀jẹ̀ ninu ijọ naa, ti oju awọn kan si hàn. A le

gbọ dídún wahala, pẹlu awọn eniyan ti wọn npohunrere ti wọn si nkigbe ni abẹlẹ: Wọn kọkọ tẹ fidiò naa jade laisi akọle. Àsọlé ti ko to 50 [aadọta] wa nibẹ. Lara awọn ti Ìgbìmọ̀ naa ri ni adura fun awọn ti o fi ara káàṣá, awọn ami igbe kike, pẹlu awọn gbolohun nipa aabo ni Nigeria. Ẹni ti o ṣe atẹjade naa fesi si ọpọlọpọ lara wọn ti o nṣe afihan ibakopọ pẹlu awọn ero ọkan wọnyẹn.

Lẹyin ti olulo naa ti tẹ àkóónú naa jade, ọkan lara awọn ibi ifipamọ Iṣẹ Ifiwera Iroyin ati Àkóónú Iwa Ipa ati Aworan ti Meta da a mọ, eyi ti o ni fidiò kan ti o jọ ọ ni ọna ti o jọju. Ibi ifipamọ yii maa nfunra rẹ pe akiyesi si àkóónú ti awọn eniyan oluyẹwo ti da mọ tẹlẹ gẹgẹ bi eyi ti o ntapa si awọn ofin ile iṣẹ naa. Ni ti ọran yii, ibi ifipamọ naa taari fidiò olulo naa si ibi irin iṣẹ kan ti o nfunra rẹ ṣe abojuto àkóónú kan ti a npe ni klasifayà, ti o le ṣe ayẹwo bi o ti ṣeeṣe ki àkóónú kan tapa si ilana Meta kan. Klasifayà pinnu pe o yẹ ki wọn fi aaye gba fidiò naa lori Instagram. O pinnu bakan naa pe àkóónú naa le ni aworan awọn iku gbigbona, latari eyi, o si funra rẹ ṣe amulo oju iworan ikilọ “disturbing content (àkóónú ti o nda ọkan ru)” gẹgẹ bi ilana Àkóónú Iwa Ipa ati Aworan ti beere. Meta ko fi to olulo naa leti pe a ti ṣe amulo oju iworan ikilọ. Laarin wakati 48 [mejidinlaadọta] ti o tẹle e, awọn olulo mẹta fi ẹsun àkóónú naa sun, titi kan ṣiṣe afihan iku ati ifarapa ti o lagbara.

Bakan naa, awọn oṣiṣẹ Meta nṣiṣẹ lati ṣe idamọ ki wọn si boju to àkóónú ti o njẹyọ lati inu akọlu naa. Oṣiṣẹ agbegbe ta ikọ ilana Meta lólobó nipa akọlu naa wọn si fi awọn fidiò iṣẹlẹ naa kun ibi ifipamọ Iṣẹ Ifiwera Iroyin Meta kan ti o yatọ, “escalations bank (ibi ifipamọ ìfẹ̀lójú)” kan. Awọn ikọ akọṣẹmọṣẹ abẹle Meta ti nri awọn àkóónú inu ibi ifipamọ ìfẹ̀lójú yii pe o ntapa si ofin, lọgan si ni a maa nyọ àkóónú yoowu ti o ba ba a mu kuro. Lara awọn fidiò ti a fi kun ibi ifipamọ ìfẹ̀lójú lẹyin iṣẹlẹ naa ni aworan ti o nfi ẹya-inu eniyan han (eyi ti fidiò ti a nsọrọ nipa rẹ ko ṣe). A pe àwọn ikọ̀ mìíràn ní Meta wá láti tọka àwọn fidiò ti o lè ri bákan náà sí ikọ̀ ìlànà náà. Nigba naa ni ikọ ilana yoo wa pinnu boya ki a fi awọn naa kun ibi ifipamọ ìfẹ̀lójú naa.

Lẹyin ọjọ mẹta ti akọlu naa ti ṣẹlẹ, Meta ṣe afikun fidio kan ti o fẹrẹ ẹ jọ àkóónú inu ọran yii si ibi ifipamọ ifẹloju naa. Latari eyi, awọn ẹrọ Meta ṣe afiwe fidiò yẹn pẹlu àkóónú ti o ti wa ni oju atẹ tẹlẹ lati ṣe ayẹwo fun ibaramu. Nigba ti ayẹwo atẹyinṣe yii nṣẹlẹ, olulo naa ṣe atunṣe atẹjade rẹ iṣaaju, o wa fi akọle ede Gẹẹsì kan kun fidiò naa. Ó nsọ pe awọn agbébọn ni o ṣe akọlu si ijọ naa, pe ọpọlọpọ eniyan ni wọn pa, o si ṣe apejuwe iṣẹlẹ naa gẹgẹ bi “eyi ti o bani ninu jẹ.” Ọpọlọpọ haṣtaagì ni o wa lara akọle naa. Eyi ti o pọju ninu awọn yii jẹ ti ere idaraya iṣe lọwọlọwọ “airsoft” (nibi ti awọn ẹgbẹ elere idaraya ti ndije lati taagì ara wọn jade kuro ninu idije naa nipa yiyin ọta ibọn onike ti a nfi awọn irin iṣẹ àgbélẹ̀rọ yin). Omiran, gẹgẹ bi Meta ti sọ, ntọka si iro ibọn wọn si tun maa nlo o lati polowo awọn ohun ija ogun. Awọn haṣtaagì miran tọka si awọn eniyan ti o nko ohun ija ogun jọ ati awọn ohun elo rẹ, pẹlu awọn ìsínnijẹ ologun.

Ni kete lẹyin ti o fi akọle naa sii, agbeyẹwo atẹyinwa ti ibi ifipamọ ìfẹ̀lójú ṣe afiwe atẹjade olulo naa pẹlu fidiò aipẹ kan ti o fẹrẹ ẹ jọ ọ, o si yọ ọ kuro ni oju atẹ naa. Olulo naa bẹbẹ. Eniyan oluṣeto kan gbe àkóónú naa yẹwo o si fi ara mọ ipinnu iyọkuro naa. Lẹyin eyi ni olulo naa tun bẹ Ìgbìmọ̀ naa.

Ni ikorita yii, a ko tii ṣe agbeyẹwo awọn ẹsun mẹta ti awọn olulo ti fi sun lori àkóónú naa a si pa a de. Meta sọ fun ìgbìmọ̀ naa pe nṣe ni wọn ṣe aṣiṣe ti wọn yan awọn ẹsun naa si ori ila iṣepataki ti o lọọlẹ.

Ni idahun si Ìgbìmọ̀ naa ti wọn nyan ọran yii, Meta ṣe agbeyẹwo fidiò ti o fẹrẹ ẹ jọ ọ naa ti a ti fi si ibi ifipamọ ìfẹ̀lójú. Meta pinnu pe ko tapa si ilana kankan nitori pe ko si “awọn ẹya ara inu ti o han sita” nitori naa ko si si akọle ti o nbani lọkan jẹ́, wọ́n si yọ ọ kuro ninu ibi ifipamọ naa. Ṣugbọn, Meta duro lori ipinnu rẹ lati yọ àkóónú ti a nsọ yii jade, bi o ti sọ pe, niwọn igba ti ohun ti a mọ nipa iṣẹlẹ naa ati iṣafihan ibanujẹ kò maa tapa si awọn ilana, awọn haṣtaagì inu akọle naa ti olulo naa fi kun ti tapa si ọpọlọpọ ilana. Ni idahun si awọn ibeere lati ọdọ Ìgbìmọ̀ naa, Meta ṣe atupalẹ itan atẹjade olulo naa o si rii pe olulo naa ti fi iru awọn haṣtaagì bẹẹ sii ninu ọpọlọpọ awọn atẹjade Instagram rẹ ẹnu aipẹ yii.

Ìgbìmọ̀ naa fiyesii awọn itan iwa ipa ati awọn iṣẹlẹ iṣẹrubalu aipẹ yii ni Nigeria gẹgẹ bi itọkasi. Awọn akọṣẹmọṣẹ ti Ìgbìmọ̀ naa fi ọrọ lọ sọ pe ijọba Nigeria ti pa riroyin awọn iṣẹlẹ iṣẹrubalu ni abẹle lẹnu mọ ni awọn akoko kan ṣugbọn ko dabi ẹni npe wọn ti ṣe bẹẹ de aaye ti o lapẹẹrẹ ni ti akọlu Ọjọ 5, Oṣu Kẹfa, ti awọn ibudo iroyin ibilẹ sọ nipa rẹ kaakiri. Aworan akọlu naa ati awọn ti o fi ara káàṣá rẹ ni wọn pin kaakiri lori awọn ibudo iroyin igbalode, ti o kan Instagram ati Facebook, ṣugbọn awọn ibudo iroyin ibilẹ ko ṣe afihan rẹ de aaye kan naa. Ni idahun si awọn ibeere lati ọdọ Ìgbìmọ̀, Meta fi idi rẹ mulẹ pe ijọba Nigeria ko kan si Meta nipa akọlu naa tabi beere pe ki wọn yọ àkóónú naa kuro.

## 3. Àṣẹ àti gbèndéke iṣẹ́ Ìgbìmọ̀ Májẹ̀-ó-bàjẹ́

Ìgbìmọ̀ naa ni aṣẹ lati ṣe agbeyẹwo ipinnu Meta latari ẹbẹ kan lati ọdọ olulo naa ti a yọ àkóónú rẹ kuro (Akọsilẹ Ofin 2 [ikeji], Abala 1 [ikinni]; Akọsilẹ Ofin Ibilẹ 3 [ikẹta]; Abala 1 [ikinni]).

Ìgbìmọ̀ naa le fi ọwọ si tabi yi ipinnu Meta pada (Akọsilẹ Ofin 3 [ikẹta], Abala 5 [ikarun]), ile iṣẹ naa si gbọdọ tẹle ipinnu yii (Akọsilẹ Ofin 4 [ikẹrin]). Bakan naa Meta gbodo ṣe ayẹwo si bi o ti ṣeeṣe lati ṣe amulo ipinnu rẹ nipa àkóónú ti o jọ ara wọn pẹlu aaye ti o fi ẹgbẹ ko ẹgbẹ (Akọsilẹ Ofin 4 [ikẹrin]). Lara awọn ipinnu Ìgbìmọ̀ naa le jẹ awọn gbolohun ti o ni awọn aba ti ko pọn dandan ti Meta gbọdọ dahun si (Akọsilẹ Ofin 3 [ikẹta], Abala 4 [ikẹrin]; Akọsilẹ 4 [ikẹrin]).

## 4. Orísun àṣẹ

Ìgbìmọ̀ Májẹ̀-ó-bàjẹ́ gbe awọn aṣẹ ati òdiwọ̀n yii yẹwo:

*I. Àwọn ìpinnu Ìgbìmọ̀ Májẹ̀-ó-bàjẹ́*

- “Ewi ilẹ Rusia” (ipinnu ọran 2022-008-FB-UA): Ìgbìmọ̀ naa jiroro nipa awọn ipenija ti o njẹyọ lati inu idasi akoonu ni awọn aaye ti ija ti ṣẹlẹ o si kiyesii pe ilana Àkóónú Iwa Ipa ati Ti Aworan ko ye kooro.

- “Idarukọ Taliban ninu ijabọ iroyin” (ipinnu ọran 2022-005-FB-UA): Ìgbìmọ̀ naa jiroro lori bi awọn olulo ti le sọ àsọlé lori awọn iṣe awọn ajọ aṣẹrubalu.

- “Aworan apanilẹrin ti ọlọpaa ilẹ Colombia” (ipinnu ọran 2022-004-FB-UA): Ìgbìmọ̀ naa da aba pe ki Meta mu ki ilana lati yọ àkóónú ti ko maa tapa si ofin ti a ṣeeṣi fi kun awọn ibi ifipamọ Ifiwera Iroyin kuro gbe pẹẹli sii.

- “Fidiò aworan ilẹ Sudan” (ipinnu ọran 2022-002-FB-MR): Ìgbìmọ̀ naa jiroro lori bi o ti yẹ ki a ṣe atunṣe si ki a si tan imọle si ilana Àkóónú Iwa Ipa ati Ti Aworan.

- “Awọn ifi ẹ̀hónú han ti o nṣègbè lẹyin Navalny ni Russia”(ipinnu ọran 2021-004-FB-UA): Ìgbìmọ̀ naa jiroro lori afojusun Òdiwọ̀n Awujọ Ihalẹ ati Ìdúnkokòmọ̀ni ti o tọ́.

- “Atunsọ ọrọ Nazi” (ipinnu ọran 2020-005-FB-UA): Ìgbìmọ̀ naa jiroro lori awọn àsọlé ti awọn ọrẹ ati olutẹle ẹni ti o kọ àkóónú naa fi silẹ lori rẹ̀, gẹgẹ bi atọka ohun ti o le jẹ ero ọkan ẹni ti o tẹ ẹ jade.

*II. Àwọn ìlana àtẹ̀jáde Meta:*

Ọran naa kan Awọn Alakalẹ Awujọ Instagram pẹlu Awọn Òdiwọ̀n Awujọ Facebook. Ijabọ àkóyawọ́ oṣu mẹta ikẹta ti Meta nsọ pe “Facebook at Instagram nṣe alabaapin awọn Ilana Àkóónú. Eyi tumọ si pe ti a ba ka àkóónú pe o ntapa si ofin lori Facebok, bakan naa a ka a si pe o ntapa si ofin lori Instagram.”

Awọn Alakalẹ Awujọ Instagram nsọ wipe Meta “le yọ awọn fidiò ti iwa ipa lile, ti aworan kuro lati rii daju pe Instagram wa ni yiyẹ fun gbogbo eniyan.” Eyi nso pọ mọ Òdiwọ̀n Awujọ ti Àkóónú Iwa Ipa ati Ti Aworan Facebook, nibi ti eredi ilana naa ti nsọ pe:

*Lati daabo bo awọn olulo kuro lọwọ aworan to nyọni lẹnu, a maa nyọ àkóónú ti o diidi ni iwa ipa tabi ti aworan, bi awọn fidiò ti o nṣe afihan gige ẹya ara wẹlẹwẹlẹ, awọn ẹya inu ara ti o han sita tabi awọn agọ ara ti o jona. A maa nyọ àkóónú ti o ni*

*awọn ọrọ ti o nbani lọkan jẹ́ nipa awọn aworan ti o nṣe afihan ijiya awọn ọmọniyan ati ẹranko. Ni aaye awọn ijiroro nipa awọn ọrọ pataki bi titẹ ẹtọ ọmọniyan loju, ogun jija tabi awọn iṣe iṣẹrubalu, a maa nfi aaye gba àkóónú ti aworan (pẹlu awọn gbedeke kan) lati ran awọn eniyan lọwọ lati bu ẹnu atẹ lu ki wọn si ta awọn eniyan ji nipa awọn aaye yii.*

Ilana Àkóónú Iwa Ipa ati Ti Aworan sọ pe "aworan ti o ba nṣe afihan iku eniyan kan tabi awọn eniyan nipasẹ ijamba tabi ipaniyan" ni a o gbe si ẹyin oju iworan ikilọ àkóónú ti o nyọni lẹnu. Abala "maṣe tẹ ẹ jade" ti awọn ofin naa nṣe alaye pe awọn olulo ko le tẹ awọn ọrọ ti o nbani lọkan jẹ́ nipa aworan ti o nilo oju iworan ikilọ ljade abẹ ilana naa. Ó tun sọ pe a o yọ àkóónú naa kuro ti "awọn ẹya inu ara ti o han" ba wa nibẹ.

Eredi ilana Ihalẹ ati Ìdúnkokò mọ́ni Meta nṣe alaye pe o maa nyọ oniruuru akoonu kuro "nitori pe o nde awọn eniyan lọna lati ni imọlara ailewu ati nini ọwọ lori Facebook." Labẹ Ipele 4 [ikẹrin] ti awọn ofin ni pato, ile iṣẹ naa fi ofin de àkóónú ti ó "ngboriyin fun, ṣe ajọyọ tabi ṣe ẹlẹya nipa iku tabi ifarapa lile" ti awọn ẹnikọọkan.

Eredi ilana awọn Ẹnikọọkan ati Ajọ Elewu ti Meta nṣe alaye pe Meta fi ofin de "àkóónú ti o ngbe oriyin fun, nṣe atilẹyin ti o jọju tabi ṣoju fun awọn iṣẹlẹ ti Facebook ntọka si gẹgẹ bi eyi ti o ntapa si awọn iṣẹlẹ iwa ipa -- titi kan awọn akọlu iṣẹrubalu, awọn iṣẹlẹ ikorira, iwa ipa ti ọpọ eniyan fi ara káàṣá rẹ tabi igbiyanju iwa ipa ti ọpọlọpọ eniyan fi ara káàṣá rẹ." Labẹ Ipele 1 [ikinni] ti awọn ofin ni pato Meta maa nyọ igboriyin yoowu fun iru iṣẹlẹ bẹẹ kuro.

*III. Àwọn àmúyẹ Meta:*

A ṣe alakalẹ awọn amuyẹ Meta ninu ifinimọle siAwọn Òdiwọ̀n Awujọ Facebook ile iṣẹ naa si ti fi idi rẹ mulẹ pe awọn amuyẹ yii ba Instagram wi. Idiyele ti "Ohun" ni a ṣe apejuwe rẹ gẹgẹ bi "pataki julọ".

*Afojusun awọn Òdiwọ̀n Awujọ wa ni lati ṣẹda aaye kan fun sisọ ero ọkan ẹni ki a si fun awọn eniyan ni ohùn kan. Meta nfẹ ki awọn eniyan le sọrọ ni gbangba nipa awọn ọrọ ti o ṣe pataki si wọn, bi o tilẹ jẹ pe awọn kan le ma fi ara mọ ọ tabi ki wọn rii pe wọn nfa ariyanjiyan.*

Meta maa nfi gbèndeke si "Ohùn" ninu iṣẹ itọju awọn amuyẹ mẹrin, mẹta ninu wọn ni nnkan iṣe nihin:

Ailewu: *A fi ara ji fun mimu ki Facebook jẹ ibi ailewu kan. A maa nyọ àkóónú ti o le pa kún ewu ifarapa fun aabo afojuri ti awọn eniyan. Àkóónú ti o ba nhalẹ mọ awọn eniyan le páni láyà, yọ eniyan sọtọ tabi pa awọn ẹlomiran lẹnu mọ a kò si fi aaye gba a lori Facebook.*

Aṣiri: *A fi ara ji fun didaabo bo aṣiri ati ifitonileti ara ẹni. Aṣiri maa nfun awọn eniyan ni ominira lati jẹ́ ẹni ara wọn, yan bi wọn ó ti ati igba ti wọn yoo ṣe alabaapin lori Facebook ki wọn si tubọ fi irọrun ṣe asopọ sii.*

Iyì: *A ni igbagbọ pe gbogbo eniyan ni o ni iyi ati ẹtọ kan naa. A nreti pe ki awọn eniyan bu ọwọ fun iyi awọn ẹlomiran ki wọn ma si dúnkokò mọ tabi rẹ awọn ẹlomiran silẹ.*

*IV. Àwọn òdiwọ̀n ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn ní àgbáyé:*

Awọn Ilana Atọni UN lori awọn Ẹtọ Okoowo ati Ọmọniyan (awọn UNGP), ti Igbimọ awọn Ẹtọ Ọmọniyan UN fi ọwọ si ni Ọdun 2011, ṣe igbekalẹ aaye atinuwa kan fun awọn ojuṣe awọn ẹtọ ọmọniyan ti awọn okoowo aladaani. Ni ọdun 2021, Meta kede nipa Ilana Awọn Ẹtọ Ọmọniyan Ile Iṣẹ rẹ, nibi ti o ti tẹnumọ ifaraji rẹ fun bibu ọwọ fun awọn ẹtọ ọmọniyan ni ibamu pẹlu awọn UNGP. Awọn odiwọn ẹtọ ọmọniyan yii ni o fa itupalẹ ti Ìgbìmọ̀ naa ṣe nipa awọn ojuṣe ẹtọ ọmọniyan Meta ninu ọran ti a nsọ yii:

- Ẹtọ si ominira lati sọ ero ọkan ẹni: Akọsilẹ 19 [ikọkandinlogun], Majẹmu Agbaye lori Awọn Ẹtọ Ara Ilu ati Oṣelu (ICCPR), Àsọlẹ́ Gbogbogbòò Nọmbà 34, Igbimọ Ẹtọ Ọmọniyan, Ọdun 2011; Aṣoju Pataki UN lori ominira ti ero ọkan ẹni ati sisọ ọ, njabọ pe: A/HRC/38/35 (2018) and A/74/486 (2019).

- Ẹtọ si aṣiri: Akọsilẹ 17 [ikẹtadinlogun], ICCPR.

**5. Àwọn èrò ọkàn olùlò**

Ninu gbolohun rẹ si Ìgbìmọ̀ naa, olulo naa ṣe alaye pe nṣe ni oun ṣe alabaapin fidiò naa lati ta awọn eniyan ji si akọlu naa ki o si jẹ ki agbaye mọ ohun ti o nṣẹlẹ ni Nigeria.

**6. Àwọn èrò ọkàn Meta**

Meta ṣe alaye ninu eredi rẹ pe, labẹ ilana Àkóónú Iwa Ipa ati Ti Aworan, aworan, titi kan fidiò, ti o nṣe afihan iku gbigbona awọn eniyan ni wọn saba maa ngbe si ẹyin oju iworan ikilọ ti o ntọka pe o le maa yọni lẹnu. Awọn olulo ti wọn ti dagba tojuu bọ le tẹ sori rẹ lati wo àkóónú naa, ṣugbọn awọn màjèsín ko ni iru oore ọfẹ lati yan bẹyẹn. Ṣugbọn, Meta tun ṣe alaye pe nigba ti awọn ọrọ ti o nbani lọkan jẹ ba ba iru àkóónú bẹẹ rin, nṣe ni wọn maa nyọ ọ. Gẹgẹ bi alaye Meta, eyi wa lati fi opin si awọn eniyan lati ṣe iwa ipa logo tabi ṣe ajọyọ ijiya awọn miran. Meta fi idi rẹ mulẹ pe, laisi akọle kan, wọn yoo fi aaye gba fidiò naa lẹyin oju iworan ikilọ ti àkóónú ti o nyọni lẹnu. Ti o ba jẹ pe fidiò naa ni "ẹya ara inu eniyan ti o han sita," gẹgẹ bi awọn fidiò miran ti

iṣẹlẹ naa ti ni, a o yọ ọ kuro labẹ ilana Àkóónú Iwa Ipa ati Ti Aworan lai nilo awọn ọrọ ti o nbani lọkan jẹ.

Ṣaaju, Meta sọ fun Ìgbìmọ̀ naa pe ni ti ọran yii wọn ko fi to olulo naa leti nipa oju iworan ikilọ naa, tabi ilana ti wọn lo lati ṣe amulo rẹ, nitori aṣiṣe ẹrọ kan. Ṣugbọn, lẹyin bibeere ibeere siwaju sii lati ọdọ Igbimọ naa, Meta sọ ọ di mimọ pe nigba ti awọn olulo Facebook lapapọ maa ngba ifitonileti nipa fifi oju iworan ikilọ kun upẹlu eredi, awọn olulo Instagram kii gba ifitonileti.

Meta ṣe alaye pe itọni abẹle rẹ fun awọn oluṣeto, awọn Ibeere Ti A Mọ, tumọ awọn ọrọ ti o nbani lọkan jẹ gẹgẹ bi awọn ti “o ngbadun tabi nri itura lati ara ijiya/ìṣeníwọ̀sí eniyan tabi ẹranko kan.” Awọn Ibeere Ti A Mọ npese awọn apẹẹrẹ ọrọ ti o yẹ gẹgẹ bi eyi ti o nbani lọkan jẹ, ti a pin si awọn ti o nṣe afihan “gbigbadun ijiya” pẹlu “awọn idahun ẹ̀fẹ̀.” Meta tun fi idi rẹ mulẹ pe a le fi awọn ọrọ ti o nbani lọkan jẹ han nipasẹ awọn haṣtaagì ati awọn ami aworan pẹlu.

Ninu itupalẹ awọn haṣtaagì ti a lo ninu ọran yii. Meta ṣe alaye pe itọkasi didun ibọn jẹ “ifesi ẹ̀fẹ̀” si iwa ipa ti o sọ akọlu Ọjọ 5, Oṣu Kẹfa Ọdun naa da yẹpẹrẹ. Meta ṣe alaye pe haṣtaagì kan naa ni wọn lo lati polowo awọn nnkan ija. Meta tun sọ pe haṣtaagì ibọn yiyin, pẹlu haṣtaagì ti o ntọka si awọn ẹnikọọkan ti o ngba ohun ija pẹlu awọn ohun elo ohun ija, “ni a le ka si ṣiṣe iwa ipa logo ati fifi oju tinrin ijiya awọn ti o fi ara káàṣá nipa gbigbe ẹ̀fẹ̀ jade ati sisọ awọn ọrọ rere nipa awọn ohun ija ati ẹwu ti wọn fi jiṣẹ iku fun wọn.” Meta tun ṣe alaye pe haṣtaagì ti o ntọka si awọn ìsínnijẹ ologun nṣe afiwe akọlu naa pẹlu ìsínnijẹ “fifi oju tinrin ajalu naa gangan pẹlu ojulowo ifarapa ti awọn ti o fi ara káàṣá ati awujọ wọn ni iriri rẹ.” Meta tun mẹnu ba a pe awọn haṣtaagì ti o ntọka si “airsoft” ṣe afiwe akọlu naa pẹlu ere idaraya kan ni ọna ti o nṣe iwa ipa logo gẹgẹ bi ohun kan ti a ṣe fun igbadun.

Meta ṣe alaye pe akọle olulo naa ti o nsọ pe oun ko fi ara mọ iwa ipa ati pe akọlu naa jẹ ọjọ ibanujẹ “ko fi han ni ọna ti o ye kooro pe nṣe ni o npin fidiò naa lati ta awọn eniyan ji nipa akọlu naa.” Ile iṣẹ naa tun tan imọle sii pe, bi olulo naa tilẹ ṣe afihan ifẹ inu lati ta awọn eniyan ji, ilo “awọn haṣtaagì ti o nbani lọkan jẹ” yoo ṣì papa yọri si yiyọ kuro. Lati ṣe atilẹyin fun ohun ti wọn ṣe yii, Meta ṣe alaye pe awọn olulo kan gbiyanju lati yẹra fun abojuto nipa fifi ede ẹ̀tàn tabi ti o lòdì sinu atẹjade wọn. Meta ya eyi sọtọ kuro lara ipinnu Ìgbìmọ̀ naa ni ti ọran “fidiò aworan ilẹ Sudan” (2022-002-FB-FBR) nibi ti olulo ti tan imọle si ero ọkan rẹ lati ta wọn eniyan ji nigba ti wọn nṣe alabaapin àkóónú ti o nyọni lẹnu. Ni idahun si awọn ibeere Ìgbìmọ̀ naa, Meta fi to Igbimọ naa leti pe olulo naa fi awọn haṣtaagì kan naa sii ninu eyi ti o pọ julọ ninu awọn atẹjade rẹ aipẹ yii. Meta ko le sọ eredi ti olulo yii fi nlo awọn haṣtaagì kan naa leralera.

Meta tun ṣe alaye pe atẹjade olulo naa tapa si ilana Ihalẹ ati Ìdúnkokò mọ́ni ti o fi ofin de àkóónú ti o nfi iku awọn ẹnikọọkan ṣe ẹlẹya. Ni ti ọran yii, a fi oju wo haṣtaagì ti o ntọka si didun ibọn gẹgẹ bi idahun ẹ̀fẹ̀ si iwa ipa ti a fi han ninu fidiò naa.

Ni ifesi si awọn ibeere lati ọdọ Ìgbìmọ̀, Meta tun pinnu pe àkóónú naa tapa si ilana awọn Ẹnikọọkan ati Ajọ Elewu. Meta ti tọka si akọlu Ọjọ 5, Oṣu Kẹfa Ọdun gẹgẹ bi "iṣẹlẹ iwa ipa ti ọpọ eniyan fi ara káàṣá rẹ", latari eyi, àkóónú yoowu ti a ba si ka si eyi ti o ngbe oriyin fun, ṣe atilẹyin ti o jọju fun, tabi ṣoju fun iṣẹlẹ yẹn ni a fi ofin de labẹ ilana awọn Ẹnikọọkan ati Ajọ Elewu. Meta ṣe alaye pe eyi wa ni ibamu pẹlu ifaraji rẹ labẹ [Christchurch Call for Action](), ati pe oun pe akiyesi awọn alajọṣepọ ile iṣẹ si akọlu Ọjọ 5, Oṣu Kẹfa Ọdun ninu [Global Internet Forum to Counter Terrorism](). Meta ṣe alaye pe, nigba ti o jẹ pe "ori yọmi" ni o jẹ, àkóónú ti inu ọran yii dabi ẹni pe o nfi awọn ti o fi ara káàṣá akọlu naa ṣe ẹlẹya ti o si nsọrọ rere nipa awọn ohun ija ti wọn lo, nitori naa o si ni amuyẹ gẹgẹ bi igboriyin fun iṣẹlẹ kan ti a tọka si labẹ ilana rẹ.

Meta sọ pe yiyọ akoonu naa kuro ni ti ọran yii nfa idọgba ti o yẹ laarin awọn amuyẹ rẹ. Akọle olulo naa ṣe afihan aiṣe apọnle fun iyi awọn ti o fi ara káàṣá, awọn idile wọn, ati awujọ ti akọlu naa ni ipa lara rẹ -- gbogbo awọn ti o gbéwọ̀n ju idiyele ohùn olulo funra rẹ. Ni ifesi si awọn ibeere Ìgbìmọ̀ naa, Meta fi idi rẹ mulọ pe oun ko gbe awọn aaye yiyẹ fun iroyin kankan jade nipa àkóónú ti o ni aworan ti o ntapa si ilana ti o nii ṣe pẹlu akọlu Ọjọ 5, Oṣu Kẹfa Ọdun.

Lakootan, Meta ṣe alaye pe awọn igbesẹ oun ṣe deede pẹlu ofin awọn ẹtọ ọmọniyan ni agbaye, ti o nṣe alaye pe ilana oun lori awọn ọrọ òṣonú ye kooro o si wa ni arọwọto, ilana naa nni afojusun lati daabo bo awọn ẹtọ awọn ẹlomiran, pẹlu ofin ara ilụ ati aabo orilẹ-ede, gbogbo awọn igbesẹ ti ko to yiyọ kuro ko si nii le yanju ewu ifarapa. Meta tọka si idajọ Ile Ẹjọ Ẹtọ Ọmọniyan ni Ilẹ Europe ninu ẹjọ *Hachette Filipacchi Associes pẹlu France* (2007), ti o gba pe awọn akọroyin ti o ṣe atẹjade awọn aworan iku gbigbona ti ẹnikan ninu iwe àtìgbàdégbà kan ti a pin kaakiri tile-toko "mu ki ipaya awọn mọ̀lẹ́bí naa pọ sii." Meta tun tọka si àpilẹ̀kọ ọdun 2010 kan lati ọwọ Sam Gregory "Kamẹrà Ni Ibi Gbogbo: Akọsilẹ Fidiò Ti O Wa Nibi Gbogbo Nipa Ẹtọ Ọmọniyan, awọn Iru Ṣiṣe Alágbàwí Fidiò Tuntun, pẹlu awọn Agbeyẹwo ti Ailewu, Aabo, Iyi ati Ifọwọsi" ninu Iwe Àpilẹ̀kọ ti Iṣẹ Ẹtọ Ọmọniyan, ti o nṣe alaye pe "awọn itapa si ofin ti aworan ti o ga julọ" bi awọn akọlu iwa ipa "ti o tete nyi pada si ipadanu iyi, aṣiri, pẹlu ajọ, ti o si le ni fifi ara káàṣá ẹlẹẹkeji. Meta kiyesii pe ilana rẹ kii ṣe lati yọ àkóónú ti aworan, ṣugbọn lati fii si ẹyin oju iworan ikilọ, ti o ndena wiwa ni arọwọto rẹ si awọn màjèsín. O sọ pe ilana wọn lati yọ awọn ọrọ ti o nbani lọkan jẹ "maa ngbe igbesẹ kan siwaju" nitori pe "idiyele iyi gbewọn ju idiyele ohùn lọ."

Ìgbìmọ̀ naa beere ibeere 29 [mọkandinlọgbọn] lọwọ Meta, eyi ti wọn dahun 28 [mejidinlọgbọn] ninu rẹ ni kikun. Meta ko le dahun ibeere kan lori ida ninu ọgọrun awọn ijabọ̀ olulo ti wọn pade laiṣe atunyẹwo wọn ninu ọja Africa ni isalẹ Sahara.

## 7. Àwọn àsọlé ará ìlú

Ìgbìmọ̀ Májẹ̀-ó-bàjẹ́ naa gbe àsọlé́ mẹsan ti ara ilu ti o nii ṣe pẹlu ọran yii yẹwo. Ọkan lara awọn àsọlé naa ni wọn fi kalẹ Asia Pacific ati Oceania, ọkan lati Central ati South Asia, ọkan lati Middle East ati North Africa, ọkan lati Africa ni isalẹ Sahara, pẹlu marun lati United States ati Canada.

Lara awọn akori ti awọn ifikalẹ naa kan ni inilo lati tan imọlẹ si ilana Àkóónú Iwa Ipa ati Ti Aworan, pẹlu awọn ọrọ ti o kan Nigeria ni pato ti o yẹ ki Ìgbìmọ̀ naa ni imọlara rẹ nigba ti wọn ba nṣe ipinnu lori ọran yii.

Lati ka awọn àsọlé ara ilu ti wọn fi kalẹ fun ọran yii, jọwọ tẹ sori ibi yii.

## 8. Ìtúpalẹ̀ Ìgbìmọ̀ Májẹ̀-ó-bàjẹ́

Ìgbìmọ̀ naa bojuwo ibeere boya o yẹ ki a da àkóónú yii pada nipasẹ lẹ́nsì mẹta: Awọn ilana àkóónú Meta, awọn amuyẹ ile iṣẹ naa, pẹlu awọn ojuṣe ẹtọ ọmọniyan rẹ:

### 8.1 Títẹ̀lé àwọn ìlànà àkóónú Meta

Ìgbìmọ̀ naa ṣe itupalẹ mẹta lara awọn ilana àkóónú Meta: Àkóónú Iwa Ipa ati Ti Aworan, Ihalẹ ati Ìdúnkokò mọ́ni, pẹlu awọn Ẹnikọọkan ati Ajọ Elewu. Eyi ti o pọju ninu awọn ọmọ Ìgbìmọ̀ rii pe ko si ilana ti a tapa si.

*I. Àwọn àlàkalẹ̀ àkóónú*

*Àkóónú Ìwà Ipá àti Ti Àwòrán*

Eredi ilana naa nsọ pe Meta "maa nyọ àkóónú ti o ni awọn ọrọ ti o nbani lọkan jẹ́ nipa awọn aworan ti o nṣe afihan ijiya awọn ọmọniyan ati ẹranko." Ṣugbọn, o tun sọ pe o nfi aaye gba àkóónú ti aworan pẹlu awọn gbèndeke kan lati ran awọn eniyan lọwọ lati bu ẹnu atẹ lu ki wọn si ta awọn eniyan ji nipa "awọn ọrọ pataki bi titẹ ẹtọ ọmọniyan loju, ogun jija tabi awọn iṣe iṣẹrubalu." Ilana naa tun nfi aaye silẹ fun awọn oju iworan ikilọ lati ta awọn eniyan lólobó pe akoonu le da ọkan ru, titi kan ibi ti aworan ti nṣe afihan iku gbigbona. Ninu awọn alakalẹ naa ni kete ni abẹ eredi ilana naa, Meta nṣe alaye pe awọn olulo ko le ṣe atẹjade "awọn ọrọ ti o nbani lọkan jẹ nipa aworan ti a parẹ tabi fi si ẹyin oju iworan ikilọ labẹ ilana yii." Meta kii pese afikun alaye ara ilu tabi apẹẹrẹ yoowu nipa awọn ọrọ ti o nbani lọkan jẹ.

Ìgbìmọ̀ naa fi ara mọ ohun ti Meta sọ pe fidiò ti a nsọrọ nipa rẹ ninu ọran yii nṣe afihan iku gbigbona ati pe, laisi akọle, o yẹ ki o ni oju iworan ikilọ kan. Ni iyatọ si àkóónú ti inu ipinnu Ìgbìmọ̀ naa lori "fidiò aworan ilẹ Sudan," fidiò ti a nsọ yii, bi o tilẹ nṣe afihan awọn eniyan ninu àgbàrá ẹ̀jẹ̀, ko ṣe afihan awọn ẹya ara inu eniyan ti o

han, ti yoo nilo yiyọ kuro labẹ ilana naa. Ninu ọran ti "fidiò aworan ilẹ Sudan," awọn haṣtaagì rẹ tọka si ifẹ inu ti o ye kooro lati ṣe akọsilẹ awọn titẹ awọn ẹtọ ọmọniyan loju, ni abala kan Ìgbìmọ̀ naa si gbe ara le ifẹ inu ti o ye kooro ti awọn haṣtaagì yẹn ati lori aaye yiyẹ fun iroyin Meta lati da àkóónú naa pada. Ninu ọran yii, ni abala kan ayẹwo Igbimọ naa nipa akoonu naa lodi si awọn ilana akoonu Meta da lori aisi awọn ẹya ara inu eniyan ti o han, gige ẹya ara wẹlẹwẹlẹ tabi sísun ninu fidiò naa, pẹlu awọn haṣtaagì ti wọn lo. Iyatọ laarin ohun tí awọn ti o pọju ati awọn perete sọ da lori eredi tabi itumọ tí ko yẹ ki a ka pẹlu awọn haṣtaagi naa ninu ọran yii.

Awọn ti o pọju ninu Ìgbìmọ̀ naa gbe ero wọn lori ilo awọn haṣtaagì ti o wọpọ lati ọwọ awọn olulo lati ṣe igbelarugẹ atẹjade kan laarin awujọ kan, ki a si ni ibaṣepọ pẹlu awọn ẹlomiran ti wọn nṣe alabaapin iru nnkan naa ti wọn si ntọka ajọṣepọ. Nigba ti a ba lo wọn bayii, kii ṣe pe wọn diidi ntumọ si àsọlé lori aworan tabi ọrọ kan. Eyi ti o pọju ninu Ìgbìmọ̀ naa rii pe awọn haṣtaagì inu akọle naa ko maa bani lọkan jẹ, niwọn bi wọn ko ti lo wọn ni ọna ti o nṣe afihan pe olulo naa "ngbadun tabi ri itura" lati ara ijiya awọn ẹlomiran. Titumọ atokọ awọn haṣtaagì iṣọwọ-huwa ti o gun naa gẹgẹ bi àsọlé lori fidiò naa jẹ àṣìdarí ninu ọran yii. Eyi nṣe iyatọ laarin ipinnu Ìgbímọ̀ naa ni ti ọran "fidiò aworan ilẹ Sudan," ninu eyi ti awọn haṣtaagì ntọka si ero ọkan olulo ti o fi nṣe alabaapin fidiò ti aworan kan ni ọna ti o ye kooro. Bi olulo ti fi awọn haṣtaagì nipa ere idaraya airsoft kun u, pẹlu awọn ti o nii ṣe pẹlu awọn ìsínnijẹ ohun ija ati ologun, ni ko yẹ ki a ka si "gbigbe oriyin fun iwa ipa" (labẹ ilana awọn Ẹnikọọkan ati Ajọ Elewu) pẹlu eyi ti o si dinku gẹgẹ bi "ṣiṣe ẹlẹya" (labẹ ilana Ihale ati Ìdúnkokò mọ́ni) tabi ṣiṣe afihan pe olulo naa "ngbadun tabi nri itura lara ijiya awọn ẹlomiran" (labẹ ilana Iwa Ipa Ti Aworan). Ọpọlọpọ olulo ojuko iroyin igbalode ni wọn ní ti wọn si nṣe alabaapin awọn ifẹ ti wọn ni si airsoft, awọn ohun ija, tabi ìsínnijẹ ologun wọn si le lo awọn haṣtaagì lati ṣe asopọ pẹlu awọn ẹlomiran lai si ṣiṣe atilẹyin fun iṣẹrubalu tabi iwa ipa lodi si awọn ẹnikọọkan ni ọna kankan. Haṣtaagì airsoft tubọ ni nnkan iṣe taara pẹlu itara fun ere idaraya, wọn ko si, lapapọ, ni ibamu pẹlu àkóónú ti fidiò pẹlu àsọléi ti olulo naa pin ni isalẹ rẹ gangan. Ó yẹ ki eyi ti tọka si Meta pe olulo naa ngbiyanju lati ta awọn eniyan ti wọn maa nsaba ba sọrọ lori Instagram ji, ki wọn si kan si ara wọn. Agbekalẹ Instagram maa nṣe iwuri fun fifi ominira lo awọn haṣtaagì gẹgẹ bi ọna lati gbe àkóónú larugẹ ki wọn si sopọ pẹlu awọn eniyan tuntun, o ṣe pataki ki Meta kiyesara ki wọn to ka lilo wọn si láìfí. Iṣẹ iwadii adaṣe ti Igbimọ naa gbe kalẹ fi idi rẹ mulẹ pe awọn haṣtaagì ti wọn lo ninu atẹjade yii ni wọn saba maa nlo laarin awọn onitara airsoft pẹlu ohun ija, Meta ko si rii pe wọn ti lo awọn haṣtaagì yii gẹgẹ bi lilo arekereke lati fini ṣe ẹlẹya lati yẹra fun didamọ ni awọn oju atẹ rẹ.

Fun awọn ti o pọju, o tun ye kooro pe àsọlé̩ ti olulo naa fi kun fidiò naa, lẹyin ti a fi oju iworan ikilọ bo o, ko tọka sii pe o ngbadun tabi ri itura lati ara akọlu naa. Olulo naa sọ pe akọlu naa jẹ apẹẹrẹ "ọjọ ibanujẹ" kan, ati pe oun kii ṣe atilẹyin fun iwa ipa. Awọn àsọlé lori atẹjade naa tubọ tọka sii pe ohun ti ó ni lọkan yé awọn olutẹle olulo naa gẹgẹ bi tita awọn eniyan ji, bii ipo ti nnkan wa ni ti ọran "Atunsọ ọrọ Nazi." Awọn idahun olulo si awọn àsọlé̩ yẹn tun ṣe afihan alekun ibanikẹdun pẹlu awọn ti o fi ara

káášá iṣẹlẹ naa. Ìgbìmọ̀ naa gba pe ariyanjiyan Meta pe awọn gbolohun olulo ti o yeni ninu akoonu naa pe wọn kii ṣe atilẹyin fun iwa ipa ni ko yẹ ki a dede gba wọle bẹẹ ni gbogbo igba, niwọn bi awọn olulo kan ti le gbiyanju lati yẹra fun abojuto nipa fifi wọn sii, lodi si eredi awọn atẹjade wọn gangan. Igbimọ naa nranti ohun ti wọn ri pe ko nii yẹ ki o pọn dandan ki olulo kan lati bu ẹnu atẹ lu nigba ti wọn ba nṣe àsọlé awọn iṣe ajọ aṣerubalu taara, ati pe nini ireti pe ki wọn ṣe bẹẹ le di ọrọ sisọ lọwọ gidigidi ni awọn agbegbe ti iru awọn ẹgbẹ bẹẹ ti lẹ́nu (wo ipinnu Igbimọ naa ni ti ọran “Idarukọ Taliban ninu ijabọ iroyin).”

Awọn perete ninu Ìgbìmọ̀ naa fi ẹnu ko pe nigba ti wọn ba wo gbogbo rẹ papọ, fifi awọn haṣtaagì ti o nii ṣe pẹlu ibọn yiyin we aworan naa jọ eyi ti o nbani lọkan jẹ, fifi pipa awọn ti a fi han yẹn we ere idaraya ati ihuwa bi ẹni pe a nṣe igbelarugẹ awọn ohun ija ti o nsín awọn ti wọn lo ninu akọlu yẹn jẹ. Eyi yoo jọ bi ẹni pe o bani lọkan jẹ fun awọn ti o móríbọ́ ninu akọlu naa pẹlu awọn mọ̀lẹ́bí awọn ti o kú, ṣiṣeeṣe ipaya ko si nii dinku nipasẹ fifi àkóónú naa si ẹyin oju iworan. Ti a ba wo ipo ti iwa ipa iṣẹrubalu wa ni Nigeria, awọn perete rii pe Meta jare lati fi si iha ikiyesara nibi ti àsọlé lori iwa ipa aworan ti jọ eyi ti o nbani lọkan jẹ, bi o ba tilẹ jẹ pe ko lọ taara de aaye kan. Eyi diidi ni nnkan iṣe pẹlu akoonu bii ti fidiò yii, nibi ti awọn kan ti o fi ara káášá iṣẹlẹ naa ti ṣe e damọ bi oju wọn ti hàn. nibi ti iwa ipa ti o nfẹju tabi igbẹsan siwaju sii lodi si awọn ti o moribọ lati ọdọ awọn ti o ṣe akọlu ti ṣeeṣe. Awọn perete ninu Igbimọ naa tun rii pe awọn gbolohun inu akọle inu ọran yii ko tako ipa ibanilọkanjẹ ti fifi awọn haṣtaagì ti o ni nnkan iṣe pẹlu ibọn we fidiò kan ti o nṣe afihan abajade abanilẹru ti iwa ipa ti wọn fi ibọn ṣe. Nigba ti awọn haṣtaagì le ṣe ojuṣẹ ibaṣepọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ awujọ kan, awọn perete ninu Ìgbìmọ̀ naa ni igbagbọ pe o boju mu, ni awọn aaye bi iru eyi, fun Meta lati ṣe amulo awọn ilana rẹ ni ọna ti o nfi oju wo àkóónú naa lati oju iwoye awọn ti o móríbọ́ pẹlu awọn idile awọn ti o fi ara káášá ninu iṣẹlẹ naa.

O tun ṣe pataki lati ṣe agbeyẹwo bi Meta ti le ṣe imuṣẹ awọn ilana àkóónú rẹ kánkán ni awọn akoko lààsìgbò, bii ti abajade awọn iwa iṣẹrubalu nibi ti aworan ti tete maa ntan kaakiri awọn ojuko iroyin igbalode. Awọn pere ka a si pataki pe alabojuto tabi olukawe lasan kan ko nii mọ pe olulo naa ti nfi awọn haṣtaagì yii si eyi ti o pọ julọ ninu awọn atẹjade rẹ ti aipẹ yii. Ni akoko ti iṣẹlẹ nṣẹlẹ kiakia, awọn perete rii pe Meta jánà lati tumọ ilo awọn haṣtaagì ti o nii ṣe pẹlu awọn ohun ija gẹgẹ bi eyi ti o ntọka sii pe o nri igbadun lati ara ijiya ti a fihan. Awọn ti o pọju gba pe yiyọ akoonu naa kuro jẹ aṣiṣe ti o lapẹẹrẹ wọn si fi ara mọ ohun ti Meta sọ pe o jẹ “ohun ti o ṣoro yanju.” Sibẹsibẹ, itupalẹ adaṣe ti Igbimọ naa (ti awọn akọṣẹmọṣẹ ṣe iranlọwọ fun nipa pipese ifitonileti ti o ba a mu lori ibọn yiyin, lori iwa ipa ni Nigeria lapapọ ati ibaṣepọ rẹ pẹlu awọn ojuko iroyin ìgbàlódé, ati lori itumọ ati ilo awọn haṣtaagì) ṣe nyọri si ki awọn ti o pọju fi ẹnu ko pe aṣiṣe ni lati ka awọn haṣtaagì yii si eyi ti o bani lọkan jẹ nitori pe wọn nii ṣe pẹlu awọn olulo ohun ija nikan.

*Ìhàlẹ̀ àti Ìdúnkokò mọ́ni*

Ipele 4 [ikẹrin] ti ilana Ihalẹ ati Ìdúnkokò mọ́ni fi ofin de àkóónú ti o nfi iku tabi ifarapa ti o le ti awọn ẹnikọọkan ṣe ẹlẹya.

Fun awọn eredi kan naa ti a to kalẹ ni abala ti o kọja, eyi ti o pọju ninu awọn ọmọ Ìgbìmọ̀ naa rii pe akoonu naa kii ṣe ifini ṣe ẹlẹya, niwọn bi eredi awọn haṣtaagì naa kii tii ṣe igbiyanju lati ṣe ẹfẹ ṣugbọn igbiyanju lati ba awọn ẹlomiran ṣe pọ, awọn idahun si atẹjade naa ati ibaṣepọ olulo pẹlu wọn ti fi idi eyi mulẹ. Meta ṣe aṣiṣe nipa nini i lọkan ṣaaju pe akojọpọ awọn haṣtaagì jẹ̀ àsọlẹ́ nipa fidiò ti a ṣe alabaapin rẹ naa. Gẹgẹ bi a ti fiyesii loke yii, o dabi ẹni pe awọn idahun si atẹjade naa ti o nṣe afihan ijaya ati ibanikẹdun jẹriisii pe olulo naa ko maa sọ wipe ki awọn onitara ohun ija fi awọn ti o fi ara káàṣá ninu iṣẹlẹ naa ṣe ẹlẹya, eyi ti Meta fi idi rẹ mulẹ pe o wa lati ọdọ awọn olulo ti o pọ julọ ni Nigeria, ati ibaṣepọ olulo naa pẹlu awọn idahun yẹn (wo ipinnu Ìgbìmọ̀ naa ninu ọran “atunsọ ọrọ Nazi.” Nigba ti awọn ti o pọju gba pe o ṣe pataki lati gbe awọn iwoye awọn ti o mori bọ ati awọn idile awọn ti o fi ara káàṣá yẹwo, awọn idahun si àkóónú yii ntọka sii pe awọn iwoye yẹn ko diidi tako fifi àkóónú naa silẹ si oju atẹ, ni pato ti a ba wo bi awọn akọlu si awọn Kristiani ni Nigeria ti ṣe lemọ́lemọ́.

Ẹnikan lara awọn perete Ìgbìmọ̀ naa ko fi ara mọ ọ. Nipa fifi awọn haṣtaagì ti o nni ṣiṣe awokọṣe awọn ohun ija kun u o tun dabi ẹni pe olulo naa diidi ndari fidiò kan ti o nṣe afihan awọn ti o fi ara káàṣá iṣẹlẹ ibọn yiyin fun awọn onítara ohun ija. Meta jánà lati rii pe eyi jọ ifini ṣe ẹlẹya, o si yẹ fun ile iṣẹ naa lati ka iwoye awọn ti o móríbọ́ pẹlu awọn idile awọn ti o fi ara káàṣá ni ṣiṣe agbeyẹwo yii.

*Àwọn Ẹnìkọ̀ọ̀kan àti Àjọ Elewu*

Ipele 1 [ikinni] ti ilana awọn Ẹnikọọkan ati Ajọ Elewu fi ofin de àkóónú ti o ngboriyin fun, ṣe atilẹyin ti o jọju, tabi ṣoju fun “iwa ipa ti ọpọ eniyan fi ara káàṣá rẹ.” Ìgbìmọ̀ naa fi ara mọ ọ pe ni ibamu pẹlu itumọ ti Meta fun “iwa ipa ti ọpọ eniyan fi ara káàṣá rẹ,” akọlu Ọjọ 5, Oṣu Kẹfa Ọdun ni amuyẹ rẹ. Ṣugbọn, awọn ti o pọju rii pe ilo awọn haṣtaagì ninu akọle naa kii ṣe “igboriyin” fun akọlu naa, eredi kan naa ti ko fi bani lọkan jẹ.

Awọn pere ko fi ara mọ wọn si rii pe, bi o tilẹ jẹ pe ori yọ mi ni o jẹ, fun awọn eredi kan naa ti a ṣe alaye rẹ ni awọn abala atẹyinwa, ifiwera laarin awọn haṣtaagì ati àkóónú ni a le wo gẹgẹ bi igboriyin fun akọlu naa funra rẹ.

*II. Ìgbésẹ̀ ìmúṣẹ*

Meta ti kọkọ fi to Igbimọ naa leti pe wọn ko fi iṣẹ riran kan ṣọwọ si olulo naa nigba ti wọn fi àkóónú rẹ si ẹyin oju iworan ikilọ nitori ọrọ ti o nii ṣe pẹlu ẹrọ. Ṣugbọn, ni idahun si awọn ibeere lati ọdọ Ìgbìmọ̀ naa, Meta ṣe iwadii wọn si pinnu pe wọn kii fi

to awọn olulo leti nigba ti wọn ba fi akoonu wọn si ẹyin oju iworan ikilọ. Ni ti ọran yii, fifi akọle kan kun u ninu eyi ti olulo ti ṣe alaye ni ẹkunrẹrẹ pe oun kii ṣe atilẹyin iwa ipa le ti jẹ igbiyanju lati dahun si fifi ipa lo oju iworan ikilọ naa. O yẹ ki Meta rii daju pe gbogbo awọn olulo ni wọn fi to leti nigba ti wọn ba fi àkóónú wọn si ẹyin awọn oju iworan ikilọ, ki a si sọ fun wọn eredi ti a fi gbe igbesẹ yii.

Ìgbìmọ̀ naa kiyesii pe nitori pe fidiò naa ba fidiò kan ti o jọ ọ ti a ṣeeṣi fi kun ibi ifipamọ ìfẹ̀lójú ti o maa nfunra rẹ yọ àkóónú ti o ba ba ara wọn mu kuro ni wọn ṣe yọ àkóónú inu ọran yii kuro. Ninu ọran ti "aworan apanilẹrin ti ọlọpaa ilẹ Colombia, Igbimọ naa sọ pe awọn ni awọn agbekalẹ ti o lọọrin pẹlu awọn igbesẹ ayẹwo lati ṣe ayẹwo àkóónú ki wọn to fi kun awọn ibi ifipamọ Iṣẹ Ifiwera Iroyin ti o maa npa awọn nnkan ti o ba ti ba ara wọn mu rẹ laisi ayẹwo ṣaaju sii. Ó yé Ìgbìmọ̀ naa pe nigba abajade kánkán ti làásìgbò kan, o ṣeeṣe ki Meta maa gbiyanju lati rii daju pe àkóónú ti o ntapa si ofin ko maa tan kaakiri awọn oju atẹ rẹ̀. Ṣugbọn, pẹlu awọn ipa ti o ndi pupọ tí awọn ibi ifipamọ Iṣẹ Ifiwera Iroyin, awọn idari ṣi ṣe pataki. O yẹ ki Meta rii daju pe gbogbo akoonu ti wọn ṣeeṣi yọ kuro nitori ifipamọ ti ko tọ yii ni a da pada ki a si da gbogbo awọn ijiya yoowu pada sẹyin.

O ká Ìgbìmọ̀ naa lara pe wọn ko ṣe agbeyẹwo awọn ijabọ awọn olulo mẹta naa nipa àkóónú naa ni ọjọ marun ti o ṣaaju ki a to yọ àkóónú naa kuro, Ni idahun si awọn ibeere lati ọdọ Ìgbìmọ̀ naa, Meta ṣe alaye pe eyi waye latari iṣoro ẹrọ kan ti wọn ko mọ ti wọn nṣe iwadii rẹ lọwọ. Ni idahun si awọn ibeere siwaju sii, Meta sọ pe awọn ko le sọ ida ninu ọgọrun awọn ijabọ olulo Instagram ni Africa ni isalẹ Sahara ti wọn ti laisi agbeyẹwo.

**8.2 Títẹ̀lé àwọn àmúyẹ Meta**

Ìgbìmọ̀ naa fi ẹnu ko pe yiyọ àkóónú inu ọran yii kuro ko wa ni ibamu pẹlu amuyẹ ti "Ohùn" Meta.

Ìgbìmọ̀ naa da awọn ifẹ inu ti o ntako ara wọn ni iru awọn aaye bii ti ọran yii mọ. Àkóónú inu ọran yii nda iyi ati aṣiri awọn ti o fi ara káàṣá akọlu Ọjọ 5, Oṣu Kẹfa Ọdun lẹbi, pẹlu ti awọn idile ati awujọ wọn. Iye kan lara awọn ti o fi ara káàṣá iṣẹlẹ naa ninu fidiò naa ni oju wọn hàn ti o si ṣeeṣe ki wọn ṣe e da mọ.

Ìgbìmọ̀ naa ranti pe ni ti ọran "fidiò aworan ilẹ Sudan" wọn," pẹlu ọran "ewi ilẹ Russia (Russian poem)" wọn, wọn pe fun ìgbé-pẹ́ẹ̀lí sii ni ti ilana Meta lori Àkóónú Iwa Ipa ati Aworan lati ba awọn amuyẹ Meta mu. Ìgbìmọ̀ naa ri bi ilana naa ti ṣe ọrọ pipin àkóónú alaworan lati "ta awọn eniyan ji" ko yeni daradara. Ninu awọn ọran kan, Igbimọ naa ti rii pe awọn oju iworan ikilọ le jẹ ọna ti o yẹ lati ṣe dọgba-ndọgba ni ti awọn amuyẹ Meta ti "Ohùn," "Aṣiri," "Iyi," ati "Ailewu" (wo ipinnu Igbimọ naa ninu awọn ọran "fidiò aworan ilẹ Sudan" pẹlu "ewi ilẹ Russia." Ìgbìmọ̀ naa fi ẹnu ko pe, ni awọn aaye ti alafo ara ilu ati ominira oniroyin ti ni gbèndéke ti ko tọ lati ọwọ ijọba,

gẹgẹ bi o ti ri ni Nigeria, amuyẹ Meta ti "Ohùn" tilẹ tubo ndi pataki sii (wo ipinnu wọn ninu ọran ti "awọn ifi ẹ̀hónú han ti Colombia"). Wọn tun fi ẹnu ko pe tita awọn eniyan ji si awọn iwa titẹ awọn ẹtọ ọmọniyan loju mọlẹ jẹ abala kan ti o diidi ṣe pataki ni ti "Ohùn," ti oun naa nṣe igbelarugẹ "Ailewu" nipa ṣiṣe aridaju anfaani si ifitonileti. Awọn oju iworan ikilọ le mu ki igbesẹ "Ohùn" yii tẹ siwaju sii, bi o tilẹ jẹ pe wọn le ma boju mu nibi ti àkóónú naa le ma ti ni aworan to niwọn bi wọn ti nṣe adinku si kikan si ara wọn ati ibaṣepọ pẹlu akoonu (wo ipinnu Igbimọ naa ninu ọran "ewi ilẹ Russia").

Fun eredi kan naa ti a la kalẹ ni abala ti o ṣaaju, awọn ti o pọju ati awọn perete ní ọpọlọpọ afẹnuko nipa ohun ti awọn amuyẹ Meta nilo fun titumọ awọn haṣtaagì ti wọn fi kun akọle fidiò naa. Awọn ti o pọju fiyesii pe o yẹ ki a diidi daabo bo "Ohùn" nibi ti àkóónú ba ti pe akiyesi si awọn itẹ ẹtọ ọmọniyan mọlẹ pẹlu awọn iṣẹ ibi ti o lagbara, titi kan awọn akọlu si awọn ijọ ni Nigeria. Awọn ti o pọju rii pe awọn haṣtaagì yii ko tako biba awọn ti o fi ara káàṣá iṣẹlẹ naa kẹdun ti olulo naa sọ, ti o han ninu akọle naa, ati pe lilo wọn wa ni ibamu pẹlu akitiyan olulo naa lati ta awọn eniyan ji. Niwọn bi akọle naa ko ti "bani lọkan jẹ," o wa ni ibamu pẹlu awọn amuyẹ Meta lati da àkóónú naa pada pẹlu oju iworan ikilọ kan ti o nfi gbèndéke si ọjọ ori. Nigba ti awọn ti o pọju gba wipe fifi oju iworan ikilọ kun u le ni ipa lori "Ohùn" nipa fifi gbèndéke si ibi ti àkóónú le de lati ta awọn eniyan ji nipa titẹ awọn ẹtọ́ ọmọniyan mọlẹ, ti a ba wo bi a ti le da awọn eniyan ti o fi ara káàṣá iṣẹlẹ naa mọ a nilo lati ṣe ni dọ́gba-n-dọ́gba ni ti awọn amuyẹ ti "Iyi" ati "Ailewu".

Awọn perete ri yiyọ àkóónú naa kuro bi eyi ti o yẹ lati daabo bo "Iyì" ati "Ailewu" awọn idile awọn ti o fi ara káàṣá Iṣẹlẹ naa pẹlu awọn ti o móríbọ́, ti wọn wa ninu ewu nla ti ipaya ẹlẹẹkeji lati ara fifi oju wina àkóónú ti o dabi ẹni pe o npese àsọlẹ́ ti o bani lọkan jẹ ti o si nfini ṣe ẹlẹya lori pipa awọn ololufẹ wọn. Ó ṣe pataki pe ọpọlọpọ oju awọn ẹni ti o fi ara káàṣá iṣẹlẹ naa fi ara han ti wọn si ṣe e damọ ninu fidiò naa ti ko si ri baibai. Ni ti "Ohùn," awọn perete rii pe wọn pin iru àkóónú kan naa laisi haṣtaagì ni oju atẹ naa lẹyin oju iworan ikilọ, o si ti le ṣeeṣe fun olulo yii lati ṣe alabaapin iru àkóónú kan naa laisi awọn haṣtaagì ti o la ohun ija lọ. Nitori naa yiyọ kuro ti Meta yọ àkóónú yii kuro ko di awọn akitiyan awujọ naa ni Nigeria lati ta awọn eniyan ji nipa, tabi beere fun ijabọ fun, awọn iṣẹ ibi yii lọna pupọ.

## 8.3 Títẹ̀lé àwọn ojúṣe ẹ̀tọ́ ọmọǹìyàn Meta

Awọn ti o pọju ninu ọmọ Ìgbìmọ̀ naa rii pe yiyọ àkóónú naa kuro ko wa ni ibamu pẹlu awọn ojuṣe awọn ẹtọ ọmọniyan Meta. Ṣugbọn, gẹgẹ bii ti ọran "fidiò aworan ilẹ Sudan," awọn ti o pọju ati awọn perete fi ẹnu ko pe o yẹ ki Meta ṣe atunṣe si ilana Àkóónú Iwa Ipa ati Aworan ki o le tan imọlẹ si awọn ilana ti o nni ipa lori àkóónú ti o fẹ ta awọn eniyan ji si titẹ awọn ẹtọ ọmọniyan loju ati tita ipa si wọn.

*Òmìnira láti sọ èrò ọkàn ẹni (Àkọsílẹ̀ 19 [ìkọkàndínlógún] ICCPR)*

Akọsile 19 [ikọkandinlogun] ti ICCPR npese aabo ti o gbooro fun ominira lati sọ ero ọkan ẹni, ti o kan ẹtọ lati wa ki wọn si gba ifitonileti. Ṣugbọn, wọn le fi gbèndéke sori ẹtọ naa labẹ awọn aaye kan ni pato, gẹgẹ bi a ti gbe e yẹwo ni ibamu pẹlu idanwo oni abala mẹta ti biba ofin mu, titọ, pẹlu aigbọdọmaṣe ati biba iye ti o jẹ mu. Ìgbìmọ̀ naa ti gba alakalẹ yii wọle lati ṣe itupalẹ awọn ilana àkóónú ati awọn iṣẹ imuṣẹ Meta. Aṣoju Pataki UN lori ominira lati sọ ero ọkan ẹni ti ṣe ìwúrí fun awọn ile iṣe iroyin ìgbàlódé ki wọn jẹ ki awọn ilana yii tọ wọn sọna nigba ti wọn ba nbojuto awọn ifi ero ọkan han lori ẹrọ ayelujara, ki wọn nii lọkan pe fifi odiwọn si fifi ero ọkan han lati ọwọ awọn ile iṣẹ aladaani ni iwọn ti wọn fẹ maa nfa awọn ifoya ti o wa fun aaye yẹn (A/HRC/38/35, paras. 45 ati 70 [ikarundinlaadọta ati aadọrin]).

*I. Bíbá òfin mu (bí àwọn òfin náà ti yè kooro tó àti bí wọ́n ti wà ní àrọ́wọ́tó sí)*

Ilana ibofinmu nbeere pe ki gbendeke yoowu lori ominira lati sọ ero ọkan ẹni ye kooro ki o si wa ni arọwọto, ki awọn ẹnikọọkan le mọ ohun ti wọn le ṣe ati eyi ti wọn ko le ṣe (Àsọlé Gbogbogboo Nọmbà 34, para 25 ati 26 [ikẹẹdọgbọn ati ikẹrindinlọgbọn). Aìlọ taara le yọri si itumọ awọn ofin ti o fi si apa kan ati imuṣẹ wọn ni ọna ti ko leto. Awọn Ilana Santa Clara lori Àkóyawọ́ ati Ìṣòtítọ́ ni Bibojuto Àkóónú, ti Meta ti fi ọwọ si, ni o rẹsẹ walẹ ni ririi daju pe awọn ile iṣẹ bọwọ fun awọn ẹtọ ọmọniyan ni ibamu pẹlu awọn òdiwọ̀n agbaye titi kan ominira lati sọ ero ọkan ẹni. Wọn la a kalẹ pe awọn ile iṣẹ gbọdọ ni “awọn ofin ati ilana ti o yeni,” titi kan “ẹkunrẹrẹ itọni ati awọn apẹẹrẹ àkóónú ti a fi aaye gba ati eyi ti a ko fi aaye gba.”

Ki wọn to yanju ilana àkóónú kọọkan, Ìgbìmọ̀ naa maa nfiyesi awọn aba atẹyinwa fun Meta lati tan imọlẹ si ibaṣepọ laarin awọn Alakalẹ Awujọ Instagram ati awọn Òdiwọ̀n Awujọ Facebook (ọran “awọn Ami Jẹjẹrẹ Ọyan pẹlu wiwa ni ihooho), 2020-004-IG-UA-2 pẹlu ọran “iyasọtọ Öcalan,” 2021-006-IG-UA-10), wọn si rọ Meta lati pari imuṣẹ aba yii bi o ba ti le ya kánkán si.

*Àkóónú Ìwà Ipá àti Ti Àwòrán*

Ìgbìmọ̀ naa tẹnumọ ifoya wọn pe ilana Àkóónú Iwa Ipa ati ti Aworan ko ye kooro to ni ti bi awọn olulo ti le ta awọn eniyan ji si iwa ipa aworan labẹ ilana naa. Ni ti ọran yii, awọn afikun ifoya wà nipa àkóónú ti a ka pẹlu itumọ Meta nipa “ohun ti o nbani lọkan jẹ.”

Ninu ipinnu ọran “fidiò aworan Sudan,” Ìgbìmọ̀ naa sọ pe:

*Ilana Àkóónú Iwa Ipa ati Ti Aworan kii tan imọlẹ si bi awọn lulo Meta ti nṣe alabaapin àkóónú aworan lati ta awọn eniyan ji si tabi ṣe akọsilẹ lilo eniyan ni ilokulo. Eredi fun Òdiwọ̀n Awujọ naa, ti o nṣe alakalẹ awọn afojusun ilana naa, kii wa ni ibamu pẹlu awon ofin ilana naa. Eredi ilana naa sọ pe Meta maa nfi aaye gba awọn olulo lati ṣe*

*àkóónú ti aworan "lati ran awọn eniyan lọwọ lati ta awọn eniyan ji nipa" titẹ awọn ẹtọ ọmọniyan mọlẹ, ṣugbọn ilana naa fi ofin de gbogbo awọn fidiò (boya wọn ṣe alabaapin rẹ lati ta awọn eniyan ji tabi bẹẹkọ) "ti awọn eniyan tabi awọn oku eniyan ti ko si ni ipo iṣegun ti wọn ba ṣe afihan gige ẹya ara wẹ́lẹ̀wẹ̀lẹ̀."*

Ìgbìmọ̀ naa da aba pe ki Meta ṣe atunṣe si ilana naa lati diidi fi aaye gba pipin aworan awọn eniyan tabi awọn oku eniyan lati ta awọn eniyan ji tabi ṣe akọsilẹ titẹ awọn ẹtọ ọmọniyan mọlẹ. Wọn tun da aba pe ki Meta ṣe agbejade awọn alakalẹ lati da awọn fidiò ti a pin fun eredi yẹn mọ. Meta ti sọ pe oun nṣe ayẹwo ìṣeéṣe awọn aba yẹn oun yoo si gbe igbesẹ agbejade ilana kan lati pinnu boya wọn le ṣe amulo wọn. Meta tun ti ṣe atunṣe si eredi ilana naa "lati rii daju pe o ṣe afihan ẹkunrẹrẹ awọn igbesẹ imuṣẹ ti ilana naa kan ki o si ṣe afikun alaye nipa pipa akoonu ti o jẹ alaworan ni ọna ti o taayọ ati awọn ọrọ ti o nbani lọkan jẹ rẹ." Ṣugbọn, Ìgbìmọ̀ naa fiyesii pe awọn ofin nipa ohun ti a le tẹ jade ati eyi ti a ko le tẹ jade labẹ ilana yii kii ṣì pese alaye nipa bi àkóónú ti a fi ofin de ti le di titẹ jade lati "ta awọn eniyan ji."

Ìgbìmọ̀ naa tun fiyesii pe lẹyin ti wọn ti kede ohun ti wọn yan ninu ọran yii ni gbangba ti wọn si fi awọn ibeere ranṣẹ si ile iṣẹ naa, Meta ṣe atunṣe si eredi ilana wọn lati fi itọkasi ìfòfindè ti o wa nilẹ lori awọn ọrọ "ti o bani lọkan je" kun u. Sibẹsibẹ, wọn ko tii sọ ni gbangba ohun ti itumọ ọrọ naa jẹ, bi ilana naa ti sa nṣe àtòkọ awọn irufẹ àkóónú ti awọn olulo ko le sọ ọrọ ti o bani lọkan jẹ nipa rẹ. Ìgbìmọ̀ naa rii pe ilo ọrọ naa "ti o bani lọkan jẹ" ni awọn itumọ ti idibajẹ ati lile ti a mọ̀ọ́mọ̀ ṣe, ti ko fi taratara wa ni ibamu pẹlu itọni abẹle Meta fun awọn olubojuto, awọn Ibeere Ti A Mọ. Itọni abẹ́lé yẹn nse afihan pe itumọ ti Meta fun "ti o bani lọkan jẹ" ni a tumọ ni ọna ti o gbooro lati tan kalẹ de idahun ẹlẹfẹ tabi ọrọ rere yoowu nipa ijiya eniyan tabi ẹranko. Eyi dabi ẹni pe o nfi gbèndéke ti o tubọ lọọlẹ si fun yiyọ akoonu kuro ju ohun ti ilana ikoju ara ilu nsọ.

*Ìhàlẹ̀ àti Ìdúnkokò mọ́ni*

Labẹ ilana Ihalẹ ati Ìdúnkokò mọ́ni Meta, ile iṣẹ naa fi ofin de àkóónú ti o nfi iku tabi ifarapa ti o le ti awọn ẹnikọọkan ṣe ẹlẹya. Igbimọ naa ko rii pe bi a ti gbe ofin yii kalẹ tọka si awọn ifoya ti ofin ninu ọran yii.

*Àwọn Ẹnìkọ̀ọ̀kan àti Àjọ Elewu*

Labẹ Ipele 1 [ikinni] ti ilana yii, Meta fi ofin de igboriyin fun ohun ti a juwe rẹ gẹgẹ bi "awọn iṣẹlẹ iwa ipa ti o ntapa si ofin," isọri kan ti o kan awọn akọlu iṣẹrubalu, "iwa ipa ti ọpọlọpọ eniyan fi ara káàṣá rẹ, pẹlu pipa ọpọ eniyan." Ìgbìmọ̀ naa fiyesii pe ko dabi ẹni pe Meta ni ilana kan ti o ṣe deede nipa igba ti o maa nkede ni gbangba nipa awọn iṣẹlẹ ti o ti juwe. Laisi ifitonileti yii, awọn olulo ninu ọpọlọpọ awọn aaye le ma mọ eredi ti wọn fi yọ àkóónú wọn kuro.

*II. Àfojúsùn tí ó tọ́nà*

Ó yẹ ki awọn gbèndéke lori ominira lati sọ ero ọkan ẹni maa lepa afojusun kan ti o tọna, eyi ti o kan idaabo bo awọn ẹtọ awọn ẹlomiran, bi ẹtọ si aṣiri awọn ti o fi ara kááṣá ti o ṣe e damọ, ti o kan awọn ti o di oloogbe, ti a fi han ninu àkóónú (Àsọlé Gbogbogboo 34, para. 28 [ikejidinlọgbọn]).

Ìgbìmọ̀ naa ti ṣe ayẹwo awọn ilana mẹta tẹlẹ nipa awọn nnkan ti o wa ninu ọran yii wọn si pinnu pe ki ọkọọkan lepa afojusun ti o tọna tii ṣe didaabo bo awọn ẹtọ awọn ẹlomiran. Wọn ṣe ayẹwo ilana Àkóónú Iwa Ipa ati Awọran ninu ọran “fidiò aworan ilẹ Sudan” wọn ṣe ayẹwo Ihalẹ ati Ìdúnkokò mọ́ni ninu ọran “awọn ifi ẹ̀hónú han ti o nṣègbè lẹyin Navalny ni ilẹ Russia, wọn si ṣe ayẹwo ilana awọn Ẹnikọọkan ati Ajọ Elewu ninu ọran “Idarukọ Taliban ninu ijabọ iroyin.”

*III. Àìgbọ́dọ̀máṣe àti ìdọ́gba*

Awọn gbèndéke lori ọrọ sisọ “gbọdọ jẹ eyi ti o yẹ lati ṣe aṣeyọri ojuṣe idaabo bo wọn; wọn gbọdọ jẹ irin iṣẹ ti àtojúbọ̀ rẹ kere julọ lara awọn ti o le ṣe aṣeyọri ojuṣe idaabo bo wọn; wọn [si] gbọdọ ba awọn ifẹ inu ti wọn fẹ daabo bo mu” (Àsọlé Gbogbogboo 34, para. 34 [ikẹtalelọgbọn]).

Ìgbìmọ̀ naa ti jiroro boya awọn oju iworan ikilọ jẹ gbèndéke ti o yẹ lori ọrọ sisọ ninu ipinnu “fidiò aworan ilẹ Sudan” pẹlu ipinnu “ewi ilẹ Russia.” Àbùdá ati lile iwa ipa aworan ti jẹ ohun ti o ndari awọn ipinnu yẹn, awọn ojuṣe ẹtọ ọmọniyan Meta si ti wa ninu wahala pẹlu awọn ilana àkóónú ati awọn imulo wọn ti o sọ ni awọn akoko kan. Ọran “ewi ilẹ Russia” da lori aworan kan, ti wọn ya lati ọna jijin, nipa ohun ti o jọ oku eniyan kan. Oju rẹ ko han, ẹniyan naa ko ṣe e damọ, ko si si aworan atọka iwa ipa ti o han. Ni ti ọran yẹn, Ìgbìmọ̀ naa rii pe oju iworan ikilọ ko pọn dandan. Ni ọna ti o yatọ, ọran “fidiò aworan ilẹ Sudan” da lori fidiò kan ti o nṣe afihan ẹya ara inu eniyan ti wọn ge wẹ́lẹ̀wẹ̀lẹ̀ ti o si han, ti ẹni ti o wa nitori ọdọ rẹ yin ibọn lu. Ni ti ọran yẹn, Igbimọ naa rii pe àkóónú naa ko ni aworan to lati da fifi oju iworan ikilọ sii lare. Ipinnu keji gbara le aaye yiyẹ fun iroyin, ti wọn maa nlo lati fi aaye gba àkóónú ti o le fẹ maa tapa si ofin. Wọn lo eyi nitori pe ilana naa funra rẹ ko ye kooro lori bi a ti le ṣe amulo rẹ lati fi aaye gba àkóónú ti o nta awọn eniyan ji si titẹ awọn ẹtọ ọmọniyan loju.

Ni ti ọran lọwọlọwọ, Ìgbìmọ̀ naa fi ara mọ ọ pe, laisi awọn haṣtaagì, o yẹ ki oju iworan ikilọ kan pọn dandan lati daabo bo ẹtọ aṣiri awọn ti o fi ara kááṣá iṣẹlẹ naa pẹlu awọn idile wọn, paapaa nitori pe oju awọn ti o fi ara kááṣá iṣẹlẹ naa han wọn si mọ ibudo akọlu naa. Eyi maa njẹ ki awọn ti o fi ara kááṣá iṣẹlẹ naa ṣe e damọ, o si tubọ nii ṣe pẹlu awọn ẹtọ aṣiri wọn pẹlu awọn ẹtọ idile wọn. Awọn afihan iku naa jẹ ti alaworan ju ti ọran “ewi ilẹ Russia” lọ pẹlu, pẹlu awọn oku ti wọn wa ninu àgbàrá ẹ̀jẹ̀ ti a fihan ni ibi ti o tubọ sun mọni. Ṣugbọn, ko si gige ẹya ara wẹ́lẹ̀wẹ̀lẹ̀ ko si si “awọn ẹya inu

ara ti o han.” Ti o ba jẹ pe ikankan ninu awọn abuda yii ti wa ni wọn iba ti ni lati yọ àkóónú naa kuro tabi ki wọn ti fun u ni aaye yiyẹ fun iroyin lati fi aaye gba a ki o ṣi le wa ni oju atẹ naa sibẹ. Nigba ti oju iworan ikilọ yoo ṣe adinku si itankalẹ pẹlu ibaṣepọ pẹlu àkóónú naa, o jẹ igbesẹ ti o ba a mu lati bu ọwọ fun ọrọ sisọ nigba ti o tun nbu ọwọ fun awọn ẹtọ awọn ẹlomiran.

Eyi ti o pọju ninu igbimọ naa rii pe yiyọ àkóónú naa kuro kii ṣe gbèndéke ti o pọn dandan tabi ti o ba ẹtọ olulo lati sọ ero ọkan rẹ mu, o si yẹ ki wọn da a pada pẹlu oju iworan ikilọ ti “ohun ti o ndani lọkan ru.” Awọn ti o pọju rii pe fifi awọn haṣtaagì kun u tubọ nmu ki ewu ti ṣiṣe ipalara fun awọn ẹtọ aṣiri ati iyi awọn ti o fi ara káàṣá iṣẹlẹ naa, awọn ti o mori bọ tabi awọn idile wọn, niwọn bi fidiò ti o jọ ọ pupọ ti wa lori Instagram lẹyin oju iworan ikilọ tẹlẹ.

Nipa ṣiṣe adinku ti o pọ si iye awọn eniyan ti yoo ri akoonu naa, ṣiṣe amulo oju iworan ikilọ ninu ọran yii wa lati bu ọwọ fun aṣiri awọn ti o fi ara káàṣá iṣẹlẹ naa (gẹgẹ bi o ti ri pẹlu awọn apẹẹrẹ awọn fidio ti wọn ri bakan naa), nigba ti wọn tun nfi aaye gba ijiroro nipa awọn iṣẹlẹ kan ti awọn ipinlẹ kan le fẹ pa lẹnu mọ. Ninu aaye aisi aabo ti o nlọ lọwọ, o diidi ṣe pataki pe ki awọn olulo le ta awọn eniyan ji nipa awọn iṣẹlẹ aipẹ, ṣe akọsilẹ awọn titẹ awọn ẹtọ ọmọniyan loju, ki wọn si gbe jijiyin fun awọn iṣẹ ibi larugẹ.

Fun awọn ọmọ Ìgbìmọ̀ ti o pọju, akọle naa lapapọ, titi kan awọn haṣtaagì, ko bani lọkan jẹ yoo si nilo lati tubọ ṣe afihan ibanilọkanjẹ, ifini ṣe ẹlẹya, tabi igboriyin fun iwa ipa ni ọna ti o ye kooro ki a to le ka yiyọ kuro àkóónú naa gẹgẹ bi eyi ti o pọn dandan ti o si ba a mu.

Awọn perete ninu Ìgbìmọ̀ naa fi ara mọ awọn ti o pọju ni ti ọna itupalẹ ati iwoye wọn lapapọ nipa awọn ilana Meta ni abala yii, ṣugbọn wọn tako itumọ ti wọn fun awọn haṣtaagì, nitori naa wọn tako abajade itupalẹ ẹtọ ọmọniyan wọn.

Fun awọn perete naa, yiyọ atẹjade naa kuro wa ni ibamu pẹlu awọn ojuṣe ẹtọ ọmọniyan ati awọn ilana aigbọdọmaṣẹ ati ibamu Meta. Nigba ti awọn iṣẹlẹ bi akọlu yii ba ṣẹlẹ, lemọ́lemọ́ ni iru awọn fidiò yii maa ntan kaakiri. Olulo ninu ọran yii ni ọpọlọpọ awọn olutẹle Ó ṣe koko pe ni idahun si awọn iṣẹlẹ bi eyi, Ki Meta gbe igbesẹ kánkán ti o si pọ, titi kan nipasẹ ajọṣepọ pẹlu awọn alabaaṣepọ ile iṣẹ, lati dena ki wọn si ṣe adinku si ifarapa ti o ba ẹtọ ọmọniyan awọn ti o fi ara káàṣá, awọn ti o mórí bọ́ pẹlu awọn idile wọn. Ó tun nṣe ojuṣe ara ilu ti o fẹju sii ni ti kikoju iṣerubalu ti o tan kaakiri ti awọn ti o ṣe iru awọn akọlu bẹẹ nfẹ ṣe, ti wọn mọ pe awọn ibudo iroyin ìgbàlódé yoo fẹ ipa wọn loju ni ọkan awọn eniyan. Fun awọn perete, ko fi bẹẹ ṣe pataki ti a ba fi oju awọn ẹtọ ọmọniyan wo o boya olulo ninu ọran yii nii lọkan ṣaaju lati lo awọn haṣtaagì naa lati so pọ mọ awujọ wọn tabi ki wọn mu ki ibi ti wọn le de jinna sii. Idiyele awọn ibaṣepọ yii, si awọn ẹnikọọkan ti o kan ati awọn ara ilu lapapọ, nigba ti ko ṣe pataki, ni iṣepataki ti bibu ọwọ fun ẹtọ si aṣiri ati iyi awọn ti o mórí bọ́

ati awọn ti o fi ara kááṣá iṣẹlẹ naa ju lọ. Oju awọn ti o fi ara kááṣá han o si ṣe e damọ ni ọna ti ko jin ninu fidiò naa, ni ibi ijọsin, ti ẹ̀jẹ̀ wẹ oku wọn. Ifiwera laarin eyi ati awọn haṣtaagì ologun nipa awọn ohun ija ninu akọle naa njani laya o si dabi ẹni pe o nfini ṣe ẹlẹya. Jijẹ ki awọn ti o fi ara kááṣá pẹlu awọn idile wọn ri irufẹ àkóónú bẹẹ le mu ki wọn tun ni ipaya lẹẹkeji, bi o tilẹ jẹ pe kii ṣe ohun ti olulo naa ni lọkan niyẹn.

Fun awọn perete, eyi yatọ si ọran "fidiò aworan ilẹ Sudan," nibi ti awọn haṣtaagì ti tọka si ero ọkan lati ṣe akọsilẹ awọn itẹ ẹtọ ọmọniyan loju ni ọ na ti o han gidigidi. Nigba ti ko yẹ ki awọn gbolohun ti o yeni nipa ero ọkan lati ta awọn eniyan ji jẹ amuyẹ ilana kan (wo awọn ipinnu "ìgbànú Wampum," ati "Idarukọ Taliban ninu ijabọ iroyin"), o wa ni ibamu pẹlu awọn ojuṣe ẹtọ ọmọniyan Meta lati yọ awọn haṣtaagì ti ko fi àríwísí sọ itara ji fun awọn ohun ija pẹlu aworan awọn eniyan ti ibọn pa ti o ṣe e damọ. Ni awọn aaye yii, awọn perete ni igbagbọ pe o yẹ ki Meta ṣe aṣiṣe lati ṣe ojurere fun iyọkuro.

**9. Ìpinnu Ìgbìmọ̀ Májẹ̀-ó-bàjẹ́**

Ìgbìmọ̀ Májẹ̀-ó-bàjẹ́ naa yi ipinnu Meta lati yọ àkóónú naa kuro pada, ti o nnilo pe ki wọn da atẹjade naa pada pẹlu oju iworan ikilọ "sami sii gẹgẹ bi eyi ti o nda ọkan ru" kan.

**10. Gbólóhùn nípa ìgbaninímọ̀ràn lórí ìlànà**

Ìlànà àkóónú

1. O yẹ ki Meta ṣe atunyẹwo ìpèdè fun idojukọ awujọ ninu ilana Àkóónú Iwa Ipa ati ti Aworan lati rii daju pé ó sàn ki o ba itọni abẹle ile iṣẹ naa mu lori bi wọn yoo ti ṣe imuṣẹ ilana naa. Ìgbìmọ̀ naa yo gba pe a ti mu aba yii lo nigba ti a ba ti sọ ilana naa di ọtun pẹlu itumọ kan ati awọn àpẹẹrẹ, ni ọna kan naa ti Meta fi ṣe alaye awọn ọrọ bii "igboriyin fun" ninu ilana awọn Ẹnikọọkan ati Ajọ Elewu."

Ìmúṣẹ

2. Ó yẹ ki Meta fi to awọn olulo Instagram leti nigba ti wọn ba da oju iworan ikilọ bo àkóónú wọn ki wọn si pese eredi ilana ni pato fun ṣiṣe bẹẹ. Ìgbìmọ̀ naa yo gba pe a ti mu aba yii lo nigba ti Meta ba fi idi rẹ mulẹ pe wọn pese awọn Ifitonileti fun awọn olulo Instagram ni gbogbo ede ti oju atẹ naa ṣe atilẹyin fun.

***Àkíyèsí ìlànà:**

Awọn ajọ ẹlẹni marun ni o maa nṣeto awọn ipinnu Ìgbìmọ̀ Májẹ̀-ó-bàjẹ́ awọn ti o pọju ninu awọn ọmọ Ìgbìmọ̀ naa ni o si maa nfi ọwọ sii. Awọn ipinnu Ìgbìmọ̀ naa ko fi dandan jẹ ohun ti gbogbo ọmọ ìgbìmọ̀ naa ní lọkan.

Fun ipinnu ọran yii, wọn gbe iṣẹ iwadii àdáṣe kan funni lorukọ Igbimọ naa. Ile-ẹkọ iṣẹ iwadii àdáṣe kan ti olu ile iṣẹ rẹ nbẹ ni Yunifasiti Gothenburg ti o si nlo ikọ awọn onimọ ijinlẹ awujọ ti o le ni 50 [aadọta] ni agbegbe mẹfa, pẹlu awọn akọṣẹmọṣẹ orilẹ-ede ti o le ni 3,200 (ẹgbẹrindinlogun) kaakiri agbaye. Duco Advisors ran Ìgbìmọ̀ naa lọwọ, tii ṣe ile iṣẹ igbaninimọran kan ti o nfi oju sun ikorita tí iṣelu agbegbe, ifọkantan ati ailewu, pẹlu imọ ẹro ti pade, pẹlu Memetica, ajọ iwadii ori ẹrọ kan ti o npese imọran nipa ọrọ ewu ati iṣẹ ọtẹlẹmuyẹ ihalẹ lati ṣe adinku awọn ewu ori ẹrọ ayelujara.